The Chief Secretary to the Government

Oro Iwe Ipingun Ogbeni W. R. Harding Ologbe mbe ninu " Eko Akete t'oni

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. VI. No. 268 SATURDAY, MARCH 31, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

*[ A complete cure for old and fresh Gonorrhoea. ]*

NIGERIAN SECRETARIAT 12 APR 1928

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATOSI.

:o:

*[ Fun Atosi lailai ati tilun.]*

Ti a ko ba tete wo Atosi san daradara, o ma ndi enia lowo l... abiamo, o si ma nfa orisi arun mi wa, bi:—Jedi-jedi ... Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atosi san lawotan patapata, l o si nje ki o ri ...

...bati enyin ilu ba ri ise ribi-
... Demo ba nse nigbamiran
... o ma ri awon elomiran ti
... si awon eniti o je olotu fun awon
...irufe ise enu suti ti a nwi ni wipe opolopo
...niti o fi ara won joye ola-ilu yio ma so
...i isokuso tabi crokoro lokan ko jo okan li
...i o le mu awon eniti o je omolehin egbe na
...kero si awon Alakoso tabi Oselu ti o mbe
Egbe-Demo.

...iah
...st qu...

"AWA O MA JO, AWA O MA YỌ, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-kọ, Iso lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, ... Aganyin fi nko Ẹja-sawa Abọmalọ, ni Şọbu rẹ ... treet, (Tribute) Moloney Bridge

Pọ ọ si ni Eko.

ati

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING ...
ADEOYE DENIGA AT 24, WILL...

**Are you a Mechanic ?**—If so you must want Tools, now or soon!

**Do you intend to put up a house ?**— Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

**B. C. Vaughan's "Excel-sior" Stores**

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

**J. C. VAUGHAN**

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna: bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ o ni'ya lati ra nibẹ:

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atari-Ajanaku lọjọ to ti pẹ: bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai! bi o ri orişirişi Ọkọ ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbenagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | [illegible] |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

AGBAKO ORI EDE.

Ni lọlọyi ni a gbọ pe ọkọnrin kan lọ ka Ọgbẹni Alufa kan mọle ni eti Ẹhin-ọgba niwọn agogo mejila oru, a si gbọ pe ọkọnrin na ni bi Alufa na ko ba fun on ni owo ti on tọrọ lọwọ rẹ—owo bi nkan ṣile mẹwa tabi jubẹ lọ—on yio ṣe Alufa na ni jamba: ọgafa bẹni a sọ pe Alufa na fun ọkọnrin na ni ohun ti o tọrọ: nigbẹhin-gbẹhin ni a gbọ pe Alufa yi lọ sọ fun awọn Ọpa Ọba, ẹjọ si ti di Kotu ti Ebute Mẹta nisisiyi.

AJANAKU BABA NAMA, ERIN WO!

Pẹlu ẹdun nla ni a fi jihin iku Ọgbẹni J. H Doherty, igi owo ati oninure, ni irọlẹ Satide to koja ni ile rẹ ni Campos Square, lẹhin igbati a ti lọ ṣe etutu si oku rẹ ni Ṣọṣi Alagogo, a gbe lọwọ lọ si Ikoyi nibi isimi rẹ, a ko le ṣẹṣẹ tun ma sọ ti ero ti nwọn nwọ bi omi, nigbati a nsin oku ẹni nla yi lọ si ile Agbepẹkun; a ba gbogbo awọn ọmọ rẹ ati awọn ẹbi oku ẹni rere yi kẹdun ọfọ nla yi.

Ẹ KU ỌWỌ IṢẸ O.

A gbọ wipe iṣẹ Afara (*Idumagbo Bridge*) ti Ijọba nṣe ṣe nku sata ki a pari, a dupẹ lọwọ Ijọba fun irufẹ owo ribiribi ti nwọn nna si ori Afara na; titi ọjọ mẹta yio di ṣiṣi fun lilo, nigbana li ao ṣe itọsẹ iye ti Afara na pa lọwọ Ijọba; ki Ọlọrun jẹki o ṣ'oju ẹmi.

---

ỌRỌ ṢOKI NIPA IGBESI AIYE ỌGBẸNI JOSIAH HENRYSON DOHERTY OLOGBE.

---

A bi Ọgbẹni Josiah Henryson Doherty ni ọjọ 16 oṣu *August* ọdun 1866. Orukọ baba rẹ a ma jẹ Henry Doherty, orukọ iya rẹ si ni Ariwọọla. O fi igba kan lọ si Ile-iwe "Tulẹ" ti awọn C.M.S. nibi yi ni nwọn ma kọ enia ni iwe fun iṣẹ Tiṣa ati iṣẹ Oniwasu; lẹhin eyi o ṣe akọwe Seidu Olowu fun ọdun gbọrọ, nigbati o si ṣe o bẹrẹ si ṣe owo fun ara rẹ ni Alakoro, ni atetekọṣe on pẹlu ibatan rẹ Frederick Doherty da owo pọ, lẹhin igba diẹ nwọn pinya, o si nba owo rẹ lọ bi ti igba iṣiwaju, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti inu rere rẹ, o si ni iye awọn enia ti o ti gba silẹ lọwọ idamu ati lasigbo aiye: o ni iye owo ti o ti na si Ṣọṣi titun ti a nkọ nisisiyi ni Ṣọṣi Alagogo, ki fi Ṣọṣi lilọ jafara, o si jẹ ẹnikan ti ki iṣe bisibeke tabi alatojubọ si ọrọ ti ko ba kan; bi o ti lowo bẹ si ni Ọlọrun fi ọmọ jinki rẹ, o si niye ọmọ rẹ ati awọn ọmọ ẹlomiran ti o ti ran lọ kọ'we, ati iṣẹ ni ilu Ọba. Ọkanṣoṣo Araba t'ẹgba ọṣunṣun ni o jẹ ni ọna gbogbo.

Ki Baba maṣai f'ori jin.

---

ẸDA LO NLULU IBAJẸ ṢUGBỌN ỌLỌRUN ỌBA KO NI JẸ O DUN.

---

Lati ọwọ KEKERE AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Lai si tabitabi nigbati ẹnyin ilu ba ri iṣẹ ribi-ribi ti awọn ilu—Ẹgbẹ Dẹmọ ba nṣe nigbamiran fun rere ilu si ilẹ yi, a o ma ri awọn ẹlomiran ti yio ṣe ẹnu ṣuti si awọn ẹnti o jẹ olotu fun awọn ẹgbẹ yi, irufẹ iṣe ẹnu ṣuti ti a nwi ni wipe ọpọlọpọ awọn ẹniti o fi ara wọn joye ọla-ilu yio ma sọ orişirişi isọkuso tabi ọrọkọro lọkan ko jọ ọkan li ọran ti o le mu awọn ẹniti o jẹ ọmọlẹhin ẹgbẹ na ni erokero si awọn Alakoso tabi Oṣelu ti o mbẹ ninu Ẹgbẹ-Dẹmọ.

Awa kan sara si iṣẹ pataki ti awọn olotu nṣe nipa eyi, iṣẹ ti awa ro wipe nwọn nṣe ani ogun ti nwọn nja ti ọna ti ilẹ yi fi le rọ tẹru-tọmọ tonile-talejo ṣugbọn ti awọn apakan ti nwọn fi ara joye "KIJẸKITẸNISUWỌN" ti nwọn nda ilu ru ti nwọn nle bebe pe awọn ni nwọn mbẹ nibẹ nyi si itakarangban tabi iṣọtẹ si Ijọba lati le ma ṣe kokari riri oju 're gba

Ohun ti o mu wa fẹ sọrọ lọ sọdọ awọn ara ilẹ yi lori ni wipe ọran owo "*Income Tax*" ti Ijọba nfẹ gba yi ẹnu ilu ko dọgba si arara awọn ẹniti ọran na njẹ lẹnu tabi ti o ndun lọkan ti a ba ni ki a da ilu si ọna mẹwa a o ri idamẹsan, idakan ti o ku lo fi ọwọ sọiya wipe o tẹ awọn lọrun ti nwọn tẹ ki Ijọba gba, a fi ti ko ba wu Ijọba mọ lo ku. Ṣugbọn nwọn gbagbe wipe bi oni ti ri ọla ki iri bẹ, bẹ ni awọn Babalawo fi ndifa ọrọrun.

Ki iṣe wipe awọn Dẹmọ yan Ajoji-ilu si Igbimọ Aṣofin lati ma ta ofin-kofin ti Ijọba ba fẹ mu wa si ilu kulẹ, bẹni ki iṣe wipe lati ma kọ ẹhin si ọrọ ti Ijọba ba mu wa si Igbimọ ti o ba si kan ilu, bi awọn Aṣoju wọnyi ba tilẹ ro wipe awọn le ṣe bẹ, bi o ba jẹ ohun ti Ijọba ba fẹ ṣe, nwọn o wa ọnakọna ti nwọn o fi gbọn ju wa lọ lati gba ṣe nkan na, anbọsibọsi Ilu ko yan wọn lati ṣe gẹgẹ bi a ti wi yi, ati pẹlu awọn tikalara wọn papa ko ni irufẹ ero ti a wi yi.

Ṣugbọn bi Ijọba ba mu ọrọ tabi ofin kan wa si Igbimọ yala nwọn ti ro tabi nwon ko ni Ipade Ijọba papa eyiyi ni "*Executive Council*" ti o ba jẹ ọrọ tabi ofin ti yio ba ilu lẹru tabi ti yio fa olukuluku enia ni ilu sinu inira ati iyọnu, awọn Aṣoju ti ilu yan ti a wi yi ni lati kan si ilu yi ki nwọn si fi ohun ti nwọn ri ye ilu daradara lati gbọ ti ẹnu ilu ati lati gba labari bi nwọn yio ti ṣe lọhun.

Lẹhin ti nwọn ba ṣe ba yi tan, oju mi da wipe ti ilu ba ri wipe ijangban ni yio jẹ fun wọn, nwọn ko ni gba awọn Aṣoju wọnyi ni imọran pe ki nwọn ti Ijọba lẹnin, ti awọn apakan ti ko ṣe ti ilu ba si ri wipe ilu sorikodo lati kọ irufẹ ofin bẹ, bokanran ki nwọn dide lọtọ gẹgẹ bi nwọn ti sọ wipe awọn ko ni ba ilu ṣe pọ lailai nitori Lord Derby ọkunrin nyẹn lati fi ye Ijọba wipe nitotọ ẹnyin lẹ ni wa, ohunkohun ti ẹ ba fẹ ṣe fun wa ko si ohun ti o le di nyin lọwọ pe ki ẹ ma ṣe, irufẹ ofin bayi-bayi ti ẹ fẹ mu wa yi ko ni le wọ arara, ki nwọn ti lẹ wi bẹ ni gbolohun kan ki gbogbo ilu ri wipe nwọn gbiyanju awọn arabi ta fita-fita diẹ lọtẹ yi, bi iyanju bẹ ba tilẹ fẹ iyanju aiyederu nikan wọn, iyẹn ku si ọwọ wọn nigbana awọn ilu ko ni igbe wọn wipe nwọn nda ilu ru; eyiti nwọn ko ba fi ṣe bayi ni wipe awọn Ẹgbẹ-Dẹmọ ndi tẹmbẹlẹkun si Ijọba, nwọn ngboju ogun si wọn, ni ero pe ki nwọn le sọ wipe ẹ ṣehun, ẹnyin lẹ nṣe ti wa o jare, ṣugbọn anfani wo ni iyẹn ṣe wayi fun irufẹ wahala ti enia le ma ṣe ni ọna bayi;

Gbogbo ọna ti awọn Ẹgbẹ-Dẹmọ ba ngba lati fi to ilu to nje ọna tẹmbẹlẹkun lo si nje ọna ti ko mọ gan lori awọn ẹniti o ba ni lakaye ni lati mọ wipe ohun Ijọba ba fẹ ṣe nwọn ko je fihan enia ki enia dudu titi nwọn o fi gbe aro fi nwọn ba fẹ fi rẹ aṣọ ti nwọn nfẹ pajade, ọna ọlẹ ni nwon o si mu nkan na lati ri wipe o ṣe ti awon apakan ba si ri wipe ohun ti o le ni mu abuku ba wọn ti awọn ba fọnmu sa, ni nwọn ti ṣe nsọ wipe o dara Ijọba awọn gba ohun ti ẹ wi lori ohun ti ẹ fẹ ṣe yi, ohun ti o si nmu wọn ṣe bayi ni wipe nigbati Ijọba ti bu ẹtẹ lu wọn ni ijọhun nipa rogbodiyan owo omi.Iju.

Ẹṣin ki da ni ki a ma tun gun ni ọran ilu yi gba ni iwọn igbati ilu ti kuro ni ominira ara wọn ti nwọn ti di ọmọ abẹṣẹ Ijọba-Igẹsi lati 1861 ti Ọba Dosunmu ti fi agbara tọwọ bọ iwe Adehun eyiti o di egungun aja ti o ha awọn ara ilu Eko lọrun loni, ki a wa sọ wipe nigbati Ijọba ba ti fi agbara ṣe ohun miran si ilu, nitorina ni igbamiran bi ofin titun kan ba tun mbọ ilu ni lati dakẹ ki nwọn ma woye pe a donkiya ki nwọn gun ejika si wipe orun fẹ wo ni ki iṣe ọran ẹnikan, bi o ba nbọ bẹ dajudaju ki iṣe ipo ti ilu yi wa loni lo ma wa, a dupẹ wipe awọn onilu ti ko fẹ ki ilu o tu ko dakẹ lati tẹsẹ bọ ṣokoto nipa rere ilu wọn, ẹda lo nlu'lu ibajẹ b'Ọlọrun fẹ ko ni dun lagban rẹ.

Bi a ba sọ wipe irira ẹnikan ni nwọn nko ni nwọn fi ndagunla si ọrọ ti o ba delẹ ni ilu eyiti o ba jẹ atọwọ Ijọba wa, iyẹn badi eyiti a sọ ṣiwaju nisisiyi wipe ti Omi-Iju ni pataki julọ lai si iṣiyemeji lati igba ti rogbodiyan ti omi na ti delẹ ni awọn ara Eko ko ti roju ara wọn ni ilẹ mọ, ni tẹmbẹlẹkun ti de ọran omi na lo mu ọtẹ bọ si arin awọn Musulumi titi o fi dogun ohun ti a ko awọn Panapana wa pe ki nwọn tu omi sinu Ile Ọlọrun (*Mosjidi Li lali*) tabi *House of Lord* ni itumọ ede ti *Mosque* inago rẹ ni Mọṣalaṣi ani ninu ọdun 1916 ti awọn ojoye-ilu, saraki ilu ati ọpọlọpọ ara ilu fi lọ fi ọrọ ye ọrọ nipa ọran yi niwaju oyinbo Moorehouse pe ki o bẹ Ijọba fun awọn lati pa ofin gbigba owo-omi ni ilẹ yi rẹ, eyiti oloye ti o mbẹ ni Idoluwo nleri bebe pe kaka ki on sanwo omi ni ti on, ki nwọn kuku di ọlọ mọ on ni ikun ki nwọn lọ ju on sinu alagbalugbu omi-ọsa, ti o ba jẹ wipe irufẹ bẹ jẹ itanjẹ aiye yio si ye wọn nikun ara wọn, pẹlu bẹ na nkọ agbara agbarebọ, awọn eledekede bẹ na kọ ni nwọn tun pada jẹ sugaba pe ki Ijọba mu wọn daradara ki nwọn maṣe gbọ ohunkohun ti nwọn le ma wi irufẹ ede ti ẹnikan pe ni Igbimọ Aṣofin ti nwọn ṣe ni August 1927, pe awọn ko jare Ijọba ti o nba wọn fa ọrọ gun lọ titi nipa ọran owo-ori, ti Ijọba ko ti lo aṣẹ agbara wọn, eyiyi ni pe ki Ijọba sọ wipe awọn o fẹ gbọ ohunkohun eyi ti awọn ma ṣe ṣa ni awọn ti sọ, bẹ ni awọn ẹni yi

para sure kabakaba tọwọ bọ apo wipe şile mẹwa ti on ni yi bi o ba ya, o ya on, gbogbo ilu ni iru awọn ẹni bẹ nta kori tabi nitori ẹnikan şoşo pere? anu şe wa wipe bi o ti wu ki nwọn le şe to enia dudu ti baba atı iya wọn bi wọn bi nwọn o ma jẹ bẹ li a o si ma pe wọn lailai nwọn ko si gbodo ma dahun aiyafi ti nwọn ba sọ ara wọn di alara funfun, o wa ku bi nwọn ti ma şe si, bi nwọn ma gba ọna ilu oyinbo lọ ni pe ki nwọn ba wọn wa ohun ti yio yi ara wọn pada si funfun ki nwọn le fi ara wọn han gbangba pe awọn o ni muradi kan pẹlu enia dudu pọ mọ, şugbọn lai si eyı nibẹ oju ti wọn kolobo wọ pẹlu.

Ẹniti o ba mbẹ ni Ipade ti Ẹgbẹ-Dẹmọ şe gbẹhin ni ile Afariogun nigbati Ọlọla Dokita John Caulcrik sọ wipe ki Ọgbẹni Macaulay ka iwe ẹbẹ ji awọn fẹ şe si Ijọba nipa owo-ori ti oyinbo Birrell-Gray lẹ iwe rẹ sod*T* ni lọlọyi pe Ijọba nfẹ gba lati ọla *Sunday* ọjọ kini oşu April yi, ti Ọgbẹni Macaulay si ka a, yio ri wipe ko si ohun ti o mu ọrọ ọtẹ dani ninu rẹ si Ijọba oluwarẹ yio ri gbangba wipe rere ilu yi ni awọn olotu Ẹgbẹ yi nja fun, şugbọn sibẹsibẹ awọn ọta ilu nşd wahala wipe eyiti Ijọba nfẹ şe ni awọn ba lọrọ, awọn o fẹ mọ ohun ti awọn—ilu nsọ, awọn ko fẹ gbọ ohun ti nwi.

Ijọba ko ma so sinu ọran owo-ori wipe awọn apakan ilu ni awọn ko yan ni ipọsu nipa rẹ tobẹ ti awọn apakan fi nsọró ọtẹ si ilu pe Ijọba yio gba owo-ori, lẹhin igbati o jẹ owo-omi ti ilu nsan lọwọ yi ko da ẹnikan si, ede Ijọba ni iyẹn ohun ti nwọn ba fẹ şe gbogbo ilu lo ma ba wi: Ero ti nwọn ngba sikun o jẹ ero gọngọşu ati edidarẹ ni iwọn igbati Ijọba ko ba yi ti yi ede wọn pada gẹgẹbi a ti nsọrọ bọ.

Ohun ti awa mọ daju ninu ọran yi ni pe ki işe ilu ni nwọn ngbọtẹ si ẹniti o ba ni lakaye ni lati mọ gan lẹru pe ọna alailero ni nwọn tọ.

Bi Ẹgbẹ-Dẹmọ ba nja fun inira kan ni ilu, bi irufẹ ija bẹ ba mogan lori dajudaju o jẹ ohun ti o tọ suna loju wọn lati ja bi ija na ba muko ti Ọlọrun gba ajo ilu, o yẹ ki ilu yin wọn gidigidi, bi Ọlọrun ba si ti kadara ohun ti nwọn nja fun pe o ni lati jẹ bẹ, eyikeyi eyiowu ti o le jẹ nibẹ, o tọ o yẹ ki ilu yin wọn ki wọn si ki wọn ku işẹ; o dabi igbati a ni ẹnikan nşe aisan yala yio jẹ aisan ọlọjọ tabi amudi lasan a ni lati şe ajo fun oluwarẹ dandan bi o ba jẹ ti ọlọjọ ko si egbogi-ke-gbogi ti onişegun le lo si, şugbọn ti o ba jẹ amudi lasan ni a ma sọ wipe ara oluwarẹ san, ti o ba jẹ ti ọlọjọ ni ko si ara ti a le ba Ọlọrun da. Bi ọ ba wu Ọlọrun wahala ti Ẹgbẹ-Dẹmọ nşe bọ wa nipa owo-ori ati Ijọba lati ọjọmọjọ yi o le şe ni kadara fun wa bi o ti şe owo Omi-Iju ni kadara fun ilu Eko lati ọdun bi mẹwa di ọjọ owurọ yi, bi o ba si tun wu u, o le gba gbogbo ajo ti a ni awọn—ilu nşe abọ.

Şugbọn pẹlu bi bẹ na bi o ba jẹ wipe, Ọlọrun ko fun ilu ni kokari Ẹgbẹ-Dẹmọ ti nwọn da silẹ ti Ọlọrun na si şe "*kun* si lati wa titi di oni ani awọn ẹgbẹ yi si ni agbara lati fi Aşoju mẹta sinu Igbimọ Aşofin ati Aşoju mẹta sinu Igbimọ ilu (*Lagos Town Council*) nibo ni awon ara Eke i ba ru wo loni? ki a ma tilẹ sọ ti awọn iran isisiyi ani awọn nipa ti awọn iran ti o mbọ lẹhin ọla lẹhin igbati awọn ẹniti o nbẹ loju igba loni ba ti şe wahala fiwọn buşe ti nwọn si lọ snimi, gẹgẹ bi awọn ero işaju awọn ẹniti a ko le ma daruko nisisiyi ni Kiriyo ati Imale; tilẹ simmi.

Ẹngba ominira ilu, ẹngba ominira adugbo ẹwẹ ẹ ngba ominira ile ti olukuluku nsun ti o nji, ẹwẹ ẹ nşọtẹ si 'ra 'yin, ẹ fẹ ki okete boru mọ nyin lọwọ tan ki ẹ to şẹşẹ wa mọ wipe enia ko le ri ẹbọ abamọ şe.

Oyinbo nwa ọna ti nwọn ma fi sọ ilu di ẹru patapata, ko di igbati a ba şẹşẹ ko owo lọ si ọja lọ ra ẹru wa 'le ki a to mọ wipe lagbaja yi ẹru ni, tamẹdu ni ọmọluwabi, gbogbo ilu ati ẹniti o ni on wa ni atilẹhin ki nwọn gba owo-ori ati ẹniti o ni owo-ori ko dara ni ilu yi, lori gbogbo ilaju ti ilu Eko ni, gbogbo won li yio di ẹru nko jiyan ẹniti Ijọba ba fa oruko tirẹ ya kuro pe ko ni san, lai jẹ bayi ẹru ni olukuluku da, itijn lo jẹ fun ẹniti o mọ wipe ọmọluwabi hanhunhanhun li on nşe lati ri wipe o nsanwo ọja ti ko ra, ẹwẹ ti ko si jẹ gbese, ati pẹlu ni ipo ti ilu Eko wa loni, ọran ko si ba ilu wi, awọn ara ilu ni ọran nba wi nitori Ijọba ko ni gba owo lọwọ ile ati koriko ti o wa ni ilu, bi ko şe awọn ẹniti o nsun ti o nji ni ilu, iba jẹ onile iba jẹ alejo, iba jẹ ọmọluwabi tabi ẹniti a ra ni ẹru tẹlẹtẹlẹ.

Ẹda lo nlulu ibajẹ, şugbọn Ọlọrun Ọba ko ni jẹ o dun.

## AJANGOLOTO ẸNITI O SỌRỌ TI O LE ŞE BẸ MỌ.

Aye kosi fun wa to lọşẹ to kọja lati jibin, nipa Irun-ọdun ti awọn Imale ki lọjọ Jimọ ijẹsan.

Awa şebi awọn kan dide lọdun Ileya ti o kọja lọhun wipe Ọlọrun ma jẹki awọn ri ohun ti yio mu wọn ki Irun ọdun lọjọ Jimọ.

Awọn Ijọ meji dide lẹsi nwọn tọ Aşoju oyinbo Findlay wipe ki nwọn ba wọn yẹna Irun ti awọn Ilu nfẹ ki lọjọ Jimọ pa, ki gbogbo wọn le jumọ lọ kirun pọ lọjọ Satide, nwọn fa ọran yi lọ, nwọn fa bọ titi Oyinbo ranşẹ pe awọn Jamat—ilu pe ki nwọn so bi ti nwọn ti lọ, awọn ilu si la alaye daradara, a dupẹ wipe Ọlọrun fun Oyinbo ni lakaye ti o pe perepere dada, ko şe ohun meji o bẹrẹsi kakiri si awọn ilu ti Musulumi wa, ki a ma dalọ wonna a fi ilu Şokoto nikan li a gbọ nigbana wipe imọran ti nwọn pẹlu ti awọn Ijọ tibin ti nwọn fẹ kirun lọjọ Satide papọ, nigbati nwọn so lọ ti awọn sọ bọ, Oyinbo jẹki olukuluku lọ şe Imale rẹ

bi o ti wu, ṣugbọn nigbẹhin gbẹhin ni gbogbo aiye to wa ri kedere wipe awọn otitọ ati iwa aitọ ni ko jẹki awọn ẹniti o fẹ kirun lọjọ Jimọ hu, o si han gbangba lara wọn lọjọ—keji Satide ti nwọn lọ ki ti nwọn wipe iwa aitọ li nwọn nhu, ẹriokan awọn tikalarawọn si jẹ wọn ni gasikiya ·pe ọtẹ li nwọn di.

Nigbẹhin ti awọn ero ti o ti Hadji de bọ, gbogbo ilu lọ bere bi otitọ si nipa ariyanjiyan ọtẹ ti nwọn ṣe ni ilu, ṣugbọn awọn ero ti o bọ iati Moka sọ wipe ọna ti awọn ilu tọ eyiyi ni ọjọ—Jimọ ti nwọn mu, lo to suna, awọn Ijọ-Ọlọtẹ ti nwọn kirun lọjọ Satide loju ti.

Lori gbogbo ileri bebe ti nwọn nle ati atilẹhin gbogbo ti nwọn nṣe wipe awọn ki yio kirun lọjọ Friday lailai, o dun wa lati ri wipe ọjọ Jimọ ijẹsan ti gbogbo aiye kirun ọdun ni awọn ara bi papa ki tiwọn, wayi o, a jẹ wipe ẹnu ehoro ko gba ijanu ọrọ ti nwọn sọ nwọn o sọ bẹ mọ.

Nigbati ẹda ba ti mọ wipe ki on sórọ silẹ ki nwọn ba bẹ, tabi ki on sọrọ silẹ ki on si duro lori ọrọ na lo yẹ Ọmọluwabi, kiloṣe ti awọn Ijọ filọ kirun lọjọ Jimọ—bẹ a ko si gbọ wipe nwọn pa Malu dudu, nwọn ba tilẹ lọ si Songo lọ ra Malu dudu, ki nwọn si da dubulẹ, tani ma ba wọn jẹ? Ayamọṣebi nwọn ranṣẹ lọ si ilu Ṣokoto pe ki nwón wa ba won pin toni-toni, oju mi da wipe ti a ba fi dida ti ilẹ yi, eṣinṣin lasanlasan ko ni kun un.

Nwọn ni ki olokunrun ṣe to! o ni on o bọrọ ṣe to! to! to! Ajangoloto ẹniti o sọrọ ti o le ṣe bẹ mọ.

A tọrọ ẹmi gigun ati ilera fun Lemọmu—ilu Mọmọdu Ligali ati awọn isangbe rẹ, a tọro ilera ẹmi ati alafia ara fun Balogun—ilu Abibu Oki ati awọn ijọ rẹ, ki Ọlọrun fi ọpọlọpọ rẹ han, eke loju o ti lagbara Ọlọrun.

## AWỌN OYINBO ỌLỌKỌ—ILẸ (THE NIGERIAN RAILWAY).

Ọran ti o ba kan—ilu o kan wa, o kan Imale, ti a ko ba ni ṣe ti ete lẹṣọ awọn Imale lo ni ilu ọran kọran ti a ba ri nipa wọn, a ni lati sọ si, bi awọn Imale ba nṣe laifi kan, ọran'yan ni ki a wi, ti a ba si ri ohun ti yio jẹ ohun idena tabi ohun irẹjẹ ni sakani wọn, laifi kosi nibẹ ti a ba sọ.

Ọla Imale ni ọpọlọpọ Kiriyo omiran njẹ, Imale lo nmi si ọpọlọpọ Kiriyo miran lara, anfani ti Kiriyo si njẹ lara Imale ko lẹgbẹ. Nitorina li a tiṣe ni lati gba ọran wọn dun.

Ki iṣe wipe labẹ Imale li awa ti njẹun, bẹni ki iṣe awọn li a fi nmi boya ẹlomiran le ma sọ isọkusọ siwa nipa iba gbolohun ti a wi ṣaju nisisiyi, gẹgẹbi o ti jẹ wipe lara rere ilu li ọran awọn Imale wa lo mu wa sọrọ diẹ yi.

Ọrọ ti a fẹ sọ ni wipe a gbọ wipe awọn oyinbo ọlọkọ—ilẹ (The Nigerian Railway) ki i fun awọn Imale abẹ wọn ti o nṣiṣẹ ni Iddo laye lati ma lọ kirun—ọdun laseko ọdun wọn, gẹgẹbi a ti gbọ wipe ọpọlọpọ awọn Imale lo sibi iṣẹ lọjọ ọdun ti nwọn ṣe ni ọjọ Friday to kọja lọ yi.

Oyinbo kan ti o ṣẹṣẹ de lodun 1926 lo daba yi, o si jẹ ohun iyanu fun wa lati ri wipe oyinbo Alabojuto Ọkọ-ilẹ, E. M. Bland (General Manager of the Railway) gba irufẹ aba bẹ fun awọn Imale ti o mbẹ ni Iddo, lẹhin igbati o jẹ wipe bi Ọdun Christmas ti jẹ pataki fun awọn Railway ti nwọn fi fun awọn Kiriyo laye lati ṣe ọdun ni ile bẹ lo jẹ fun Imale papa, ikan ko yatọ si nkan nipa eyi o fẹ dabi ẹnipe o fẹ mu irẹjẹ dani, nitori eniti kole ṣe ki o ma ṣe ọdun tirẹ.

Nigbati Railway koi ti mu irufẹ aba yi, oruko ti Railway njẹ li nwọn njẹ, ko si yipada di ọjọ—oni kini Railway tun nfẹ da, tobẹ ti nwọn ko fi jẹki awọn Imale abẹ wọn ni Iddo raye lati ṣe ọdun ni ile.

*(Koi pari).*

Emi ni tiyin nitotọ,
KEKERE AWO.

---

## ẸJỌ IWE-IPINGUN TI ỌGBẸNI W. R. HARDING NI GANRAN.

*A yi si ede Yoruba lati inu Nigerian Daily Times 22/3/28.*

### OGUN HARDING.

Herbert Agbeọla Harding ati awọn mẹrin yoku pe Henry Carr ati John Randle Fourah Bay College (ọkan ninu awọn ti ogun na kan ti a si pe sinu ẹjọ yi gẹgẹ bi aṣẹ.)

Niwaju Ọlọla Adajọ M. L. TEW.

Ko si (Jury) tabi awọn agbalagba to joko lori ẹjọ pẹlu Adajọ.

Lọya awọn to pe ẹjọ ni eyi. E. A. Franklin A. Kayọde, T. A. Doherty, Jibowu ati S. R. Baptist.

Lọya awọn Baba-sinku ni Ọlọla Kitoyi Ajasa ati E. O. Moore (fun Fourah Bay College) Ọgbẹni A. Alakija ti awọn Ọgbẹni Alakija ati Alakija.

Lọya Kayọde dide o ni on ni ero lati tẹ Kotu jọrun.

Ekini :—Wipe mẹta ninu awọn ẹniti o pe ẹjọ yi jẹ ọmọ bibi Ọgbẹni Harding ti nwọn si bi wọn

lati ọwọ obinrin ti a gbe niyawo gẹgẹ bi ofin igbeyawo fun Ọgbẹni ologbe Harding gẹgẹ bi aṣẹ ati ofin igbeyawo ti Enia Dudu.

Ekeji :—Wipe nipa ti awọn yoku on ko le sọ bi iya ti nwọn ṣe iyawo tabi gbe iyawo pẹlu ologbe Harding.

Ẹkẹta :—Wipe ki on mu amu bọ ninu ekini ti on kọko sọ, on a tun wipe fun Kotu pe ni iwọn igbati Ologbe Harding gba wọn ni ọmọ, ofin papa si ni lati gba wọn bẹ wipe awọn ọmọ rẹ ni wọn nṣe ati wipe ni otọ wipe a bi Ọgbẹni Harding ni ilu Saro iyẹn ko to ko awọn ẹlẹjọ on lati ta wọn kulẹ.

Ka wa wo awọn ẹlẹri :—

Ẹlẹri ekini :—Ọrukọ mi ni Toyon, mo ba Ọgbẹni Harding lọ si Ijẹbu ni ọdun 1892 pẹlu awọn Ologun mo si sunmọ pupọ pẹki-pẹki ni mo wa si. Mo si ngbe ọkan ninu ile rẹ gẹgẹ bi ẹniti o haya ni ile ni ọwọ rẹ. Ọgbẹni yi jẹ asanwo ni Lagos *constabulary* (                ) Ọgbẹni Harding si sọ itan ara rẹ fun mi, itan aiye rẹ. O jẹ ẹniti iran rẹ jẹ Ẹgba. Awọn enia rẹ (tabi obi rẹ) nwọn ko wọn lọ si ilu Aganyin (Brazil) lẹhinna wa si Saro nibiti a gbe bi. Harding kọ ila si oju. Oye ẹbi rẹ ni Abẹokuta jẹ Lẹgun.

Ko si itako *( No cross examination )*.

Ẹlẹri Ikeji :—Orukọ mi njẹ Sẹlia Werepe, emi mo ologbe Harding. O jẹ ọkọ iya mi. Orukọ baba mi ni Werepe. O ku ni ilu Aguda (Brazil) emi wa ni Eko nigbati baba mi ku. Emi mọ bi iya mi ti ṣe fẹ Harding. Orukọ rẹ njẹ Omitunde. Iya mi-nta wosiwosi ni ita Labinjoh (Labinjoh Street) nigbati Ọgbẹni Harding nṣiṣẹ ni Bode. O ma nwa si ọdọ iya mi nigbati o ba nbọ lati bode. O ba iya mi sọrọ wipe on fẹ fi ṣe aya. Iya mi ni ọkọ on wa ni ilu Aguda (Brazli) ati pe awọn ko si ja ko to lọ si ilu Aguda. Iya mi ni on ni lati wa ẹnu awọn obi on wo ki on to le jẹ ohẹn fun, iya mi wa ẹnu iya rẹ (iya nla emi. My Grandmother) iya rẹ si ranṣẹ si Harding. Ọgbẹni Harding wa o si sọ fun gbogbo ẹbi, wọn si jẹ ohẹn si. Ọgbẹni Harding fun iya nla mi ati awọn ẹbi rẹ ni obi, orogbo, oyin ati nkan yoku pẹlu ponwun meji abọ (£2. 10. 0) o si tọrọ ibukun wọn. Iya mi ko lọ si ọdọ Harding pẹlu emi papa ati awọn aburo mi obinrin Ashinmọwu ati Memuna awọn ọmọ baba mi ati iya mi; Ọgbẹni Harding lo ran Ashinmọwu lọ si ile iwe. O si nfun iya mi ni ṣile mẹwa (10/-) lowo onjẹ lasi ko ti ko dọgba. Iya nla mi ni ile ni Mọṣalaṣi Olosun won ta ile na. Ile na jona lẹkan ri ati pe Ọgbẹni Harding lo tun kọ. O ma npe ara rẹ ni "Marra" emi ko mọ ohun to njẹ "Marra" ati pe on fẹ lọ si Abẹokuta lati lọ joye "Marra" emi ko mọ iya ati baba rẹ ṣugbọn o ma nsọ wipe awọn enia on fẹ lọ si Itako lati ọwọ Ọgbẹni Moore :—

Imale ni emi, baba mi Imale ni, ṣugbọn iya mi ki ṣe nigbati o de ọdọ Harding o ma nlọ si Ṣọṣi (*Church*) ki iya mi to lọ si ọdọ Harding oṣa lo nbọ. Iya nla mi Keferi ni ṣe orukọ rẹ ma jẹ Fadunkẹ. Emi wa yi si Imale o si yipada, Sunna rẹ Fatunmọ ni asiko ti Harding tọrọ iya mi, iya nla mi sin ẹsin Imale.

Awọn ẹbi iya mi gba adura nigbati Harding mu orẹ wa. Adura yi ki ṣe awọn Alufa Imale lo ṣe. Ọmọ ọdun mẹrindinlogun le mi jẹ nigbana, emi o si ni ọkọ. Emi mọ awọn ẹbi Harding daradara mo mọ iya Apewu, Harding a ma pe ni "ẹgbọn mi" emi ko le sọ bi ibatan wọn ti ri, ṣugbọn on lo ma sọ awọn ọmọ rẹ ni orukọ, emi mọ Mrs. Cole kan. O ti ku nisẹyin. Ọgbẹni Harding ma npe ni "Ẹgbọn mi" Imale ni baba mi ri. Iya mi ni ọmọ mẹta fun Harding orukọ wọn: Herbert Harding, Theodore Harding ati Agues Harding

Ọgbẹni Kayọde :—Emi ko ni ero lati pe ẹlẹri mi mọ lori orukọ yi.

Adajọ (*His Honour*) Ọgbẹni Moore: O ni ẹlẹri bi? Nda o. Ọlọla.

Ẹ o ri iwe ipingun na ni ọtọ ninu iwe irohin yi.

---


INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumo olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ mase gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, MARCH 31, 1928.

## OWO ASINGBA, OWO "ẸRU".

MALU TI KO NI'RU, ỌLỌRUN NI NLE EṢINṢIN FUN.

Gbogbo aiye lo mọ pe pẹlu ipa ni Ijọba fẹ fi gba owo asingba ti a ti nke ibosi rẹ pe yio ni gbogbo ilu lara lọwọ wa; nitotọ Ijọba le sọ pe, ṣe awọn Igbimọ Aṣofin lo dibo, ti ibọ fi mu gbigba owo asingba na, bẹni, ṣugbọn talo l'egun, talo ni igi oko, awọn aṣoju Eko mẹta le da ogunlọgọ awọn Oyinbo Onişẹ Ọba pẹlu Enia Dudu miran bi meji mẹta ni idi gba nigbati nwọn fi ọrọ na si didibo bi? Ki a tun da silẹ ki a ṣa: a nsan owo omi nitoriti gbogbo ilu lo nri omi na lo. a nsanwo ina, gbogbo ilu lo ngbadun awọn ina atupa Ṣango wọnyi; ṣugbọn nigbati Ijọba sofin pe ki olukuluku ọkọnrin ma wa sanwo asingba lori ohun ini rẹ lododun, kini a ba Ijọba ra o? Ni igba lailai awọn Oyinbo Gẹsi sọ pe ko yẹ ki ẹda mi'a ta ẹda ẹgbẹ rẹ bi ẹran l'ọja, Ijọba ni ko jẹ ohun ti o tọ suna fun enia ki o ma ko ẹwọn da si ẹgbẹ rẹ lọrun ki o si so mọ'lẹ lọja ni tita, gbogbo ilẹ Yoruba gba imọran yi, nwon si fi ọwọ enia tita ri'lẹ; nigbati o ṣe awọn Oyinbo Onişowo da Banki silẹ, nipa bayi awọn ti o lowo rọ'jo owo wọn sibẹ, nwon si ngba ele lori wọn, lọna bayi ọpọlọpọ aṣiri iye owo ti awọn enia ni han tun awọn Oyinbo oni Banki wọnyi, njẹ nisisiyi ti Ijọba nfẹ bẹrẹ ati ma gba owo asingba ọdọdun yi loṣu to mbọ, ko di pe ki aṣiri iye owo ti gbogbo awọn ti o ni owo si Banki ki o tu fun Ijọba nitori nwọn ko ni ṣai kan si awọn Oyinbo Oni-banki wọnyi lati mọ iye owo ti olukuluku awọn ti o fi owo sibẹ ni lori eyiti Ijọba yio bu iye owo ti nwọn ni lati san le lori; Ijọba kọ lo ba ọ ṣiṣẹ owo rẹ. Ijọba kọ lo ba ọ lãgun ki o to ri okan eji tujọ, Ijọba kọ lo ba ọ ṣiṣẹ ki o to ri afo lati ra ile meji mẹta ti o ni, sibẹsibẹ Ijọba sọ pe on ko ṣai joye Alatojubọ lati gba owo asingba yi lọwọ rẹ b'o fẹ b'o kọ, tipatipa ni ewurẹ fi njẹ ohun olohun, kini eyi bikoṣe wiwa l'oko ẹru ẹkeji: nitotọ awọn ẹlomiran le sọ pe gbigba owo asingba fẹrẹ mọ wa lara na, ati pe ṣe bẹ ni ilu ke ti nwọn si yan nigba owo omi ijelo, 'ṣe asinwa asinbọ owo omi na di gbigba tobẹ ti ọgọrọ fi nfa omi na sile: eyi le jẹ otito Ṣugbọn lori kini Ijọba sọ pe ki ilu ma san owo asingba yi lori ofo? Nigbati o ba si di ọdun die si kọ ni Ijọba yio tun fi owo kun owo ti nwọn ti fi ofin so lati san nisisiyi? Nijọwo ni a o bọ ninu ajaga Oyinbo yi, ko ha di ọjọ Agbende baun? Ogo ni awọn Oyinbo miran ka Nigeria ni oko Ifẹjẹ baba baba wọn, ti nwọn si ka awa Enia Dudu ti o mbẹ ninu rẹ gẹgẹbi "ẹru" wọn, iwa ekule j'ẹni f'ẹni ti Ijọba nhu yi ṣu wa patapata; ṣugbọn ọkan ni, ki a fi ọran wọnyi fun Ọba Sati, ki a si ma sa asajẹ yi nigbagbogbo.

Abọwọ gbọgbọrọ ti ny'ọmọ rẹ l'ọfin,
Yọ mi.

Ki Allah maṣai yọ gbogbo wa ninu ofin kofin awọn Alagbara Aiye.

---

## FUN WA NI ONJẸ OJỌ WA LONI.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU ]

Mo bẹrẹ f'oji,

Adura ti a ṣe si oke wosika yi—adura pataki ni, nitori orişa bi ifun ko si, ojojumọ lo ngba onjẹ.

Lẹhin ti Jesu ti kọ ni pe ki a juba Baba wa to nbẹ l'ọrun, ohun ti o tun kọ ni şikeji ni lati tọrọ onjẹ ọjọ wa lọwọ Rẹ; ki a to wa bẹbẹ pe ki O maşe fa wa sinu idanwo ọmọ araiye ati Bilisi Aşitani.

Olowo njẹun, talaka njẹun, ṣugbọn onjẹ ẹnikan yatọ si ti ẹnikeji; ọpọlọpọ enia nisisiyi ni ati jẹun di ẹti si lọrun. Kilo mu eyi wa, o ha ṣe pe nwọn ko ngbadura lati tọrọ onjẹ ọjọ wọn lojojumọ ni? Agbẹdọ! Njẹ bi nwọn ba ngbadura, iha ṣe pe Ọlọrun ko l'eti si ohun ẹbẹ wọn ni? Agbẹdọ!

Ṣugbọn adura laisi iṣẹ, pabo ni; owo ti ẹlomiran iba si fi jẹun sinu ara rẹ, tẹtẹ lo ma fi ta tan, ẹlomiran nna tirẹ sidi ọtẹ, ẹlomiran yio fi tirẹ mu ọti, ẹlomiran, Kotu lo ma na tirẹ si tan nibiti o gbe ndu ogun ti ko tọ si i lati jẹ; ninu ẹgbogi

awure ati ogun Madarikan ni ẹlomiran ndi alakisa si patapata. Oniruru inakuna bayi lo nsọ enia pupọ di ẹdun arinlẹ lode Eko. A ko sọ ti awọn ti ebi npa nitotọ, ti wọn si nwa iṣẹ ṣe loju mejeji, ti nwọn ko ri, tabi ti awon alatako di lọna ijẹ ti ko si ri owo fi gbo bukata rẹ mọ. Anu irufẹ awọn enia bẹ ṣe wa pupọ; adura wa si ni pe ki Ọlọrun ma ṣai pese iṣẹ anfani fun wọn, ki O ma si ṣe jẹ ki ebi inu pa wọn ku.

Ṣugbọn ẹniti o nna owo rẹ ni inakuna, ati ẹniti ko tilẹ ri iṣẹ ṣe rara nikan kọ ni ati jẹun ṣoro fun nisisiyi. O ṣoro fun oṣiṣẹ, Akọwe, Oniṣowo, ati bọkini pupọ lati jẹun yo fun ara rẹ tan, ki o si bọ gbogbo awọn ara ile rẹ ni abọyo. Kilo mu inira yi wa? Iyan! iyan!! (*Famine*) mu lode. Gari di nain (*nine pence*), ẹba ko ṣe ṣe alejo mọ.

Nitotọ gbogbo nkan ni owo rẹ ga nisisiyi ju ti atijọ lọ, ṣugbọn bi a ti le ṣai ra nkan miran ti owo rẹ ga pupọ ju, a ko gbọdọ ma ra onjẹ. Bi ẹwu kan faya, a le gbe fun Telọ (*Tailor*) fun atunṣe, bi bata gbo, a le gbe e fun Ṣumeka (*Shoemaker*) ko sọ di ọtun; ṣugbọn bi ọbẹ tan ninu iṣasun, ti gari tan ninu apo, ọgbọn wo ni ẹnikẹni le da si jn wipe ki o tọwọ bọ apo—apo tirẹ papa ni o, ko nṣe ajufu ti ẹlomiran bi ọmọ Jaguda.

Iwe-irohin kan tabi meji sọ fun wa ni lọlọ yi, idi rẹ ti gari ati ohun jijẹ miran fi wọn gogo bayi, ti mo ba si ranti daradara, nwọn gba Ijọba ni imọran wipe ki o da awọn ti o nko gari lọ ṣowo ni Cameroon, Port-Harcourt ati ibomiran duro.

Boya ti Ijọba ba ṣe bẹ nitotọ, nkan le r'ọju diẹ; yio tilẹ rọju, tabi-tabi ko si ninu eyini. Ṣugbọn awọn tilo njẹ gari pataki ni Port-Harcourt, Secondee ati Cameroon, kikoṣe awọn enia wa kanna ti o ti ilẹ yi lọ ṣowo nibẹ. Awọn ara ilu ibẹ papa, ọgẹdẹ ati koko ni nwọn njẹ ju.

Nitotọ, bi ohun jijẹ ba wọn ni ilu-oke, lọgan ni Ọba ibẹ yio paṣẹ wipe ẹnikẹni ko gbọdọ mu nkan jijẹ kuro ni ilu lati lọ fi ṣowo ni idalẹ titi onjẹ yio fi pọ ni ilu si i, ṣugbọn eyi yio jẹ ohun-ọgbin ilu na papa—ko nṣe eyiti a ko lati ilu miran lọ sibẹ.

Ara Eko pupọ lo ni oko nlanla ni Agege, Ijoko, Alagbado, Oṣhodi ati ibomiran pẹlu, ṣugbọn dipo eyiti nwọn iba gbin gbaguda, iṣu, agbado, ọpẹ, ata, iru, ẹfọ ati ohun jijẹ miran sibẹ janrẹrẹ, Cocoa ati Obi lo gba gbogbo oko kan, bẹni ṣaṣa ni ara Eko to le jẹ *chocolate* ti a fi Cocoa ṣe ni alejo, nwọn ko si mọ obi jẹ pẹlu—ṣugbọn sibẹsibẹ, bi Oyinbo ba ti ri cocoa ra, ti Hausa si nri obi ra, o tẹ awọn agbẹ Eko lọrun. Gari ti awọn papa pẹlu ọmọ wọn njẹ ko si fun tita, elubọ ko si fun tita pẹlu.

Awọn Ijẹbu Ejirin, ti Ikorodu, ti Emina, ti Ẹpẹ ati awọn Awori diẹ ṣa lo ni lati ma rin gari fun ara Eko jẹ, ki ara Ọjọ ati Badagry ma ta epo fun wọn jẹ, ki ara Jẹbba ma ta iṣu fun wọn, ki ara Bode Sadu ma ta Elubọ fun wọn, ki Hausa ma ta alubọsa ati ororo-ẹpa fun wọn, ki awọn ara Eko papa si ma ta cocoa pẹlu obi lẹhin ti nwọn ba ti jẹ gari Ijẹbu yo tan bambam,

Obinrin tabi ọdọmọbinrin Eko melo lo mọ Gbaguda lati rin ka ma ṣẹṣẹ wipe ki o yan Gari, ọmọ Eko melo lo ha le sọ Iṣu di Elubọ tabi Igbado di Ẹkọ—bẹni pataki onjẹ wa ni nwọnyi. O san pupọ larin Imale, ṣugbọn awọn ọmọbinrin Kiriyo fẹ ṣe iṣẹ akọwe Ọba. *They have left undone those things which they ought to have done and are doing those things which they ought not to have done and there is no health in them.*

Bi awọn Agbẹ (*Farmers*) Eko ko ba tete bẹrẹ si gbin Gbaguda daradara nisisiyi ki awọn obinrin wa, t'ọmọde t'agba, ki awọn alaṣọ-riro ati oniyẹri, si bẹrẹsi kọ bi a ti nṣe Gari, to ba jẹ pe ori Cocoa ati Obi ati ikilọ pe a ko gbọdọ ko Gari lọ si *Port Harcourt* ati *Secondee* mọ nikan ni o joko si ni, ki ẹnu maṣe ya wa bi Gari ba tubọ di "golu," ṣugbọn a ko gbadura ko ri bẹ rara.

Ko si ohun itiju kan ninu Gari ṣiṣe tabi tita; ọkanlawọn onjẹ ni Gari jẹ. A nṣu ṣu, a nro ro, a nwa wa, a ntẹ tẹ.

Lakotan, a bẹ gbogbo ẹniti o nta Gari ni Idumagbo, ni Ọbalende, ni Ebute Ero, Oyigbo, ni Ita Faji, Ereko, Ararọmi ati ni adugbo miran kiri, ki nwọn jọwọ din owo ti nwọn nta a nisisiyi ku nitori awọn mẹkunnu ilu, nitori awọn opo ati nitori awọn ọmọ alainibaba.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

## IN MEMORIAM.

### JOSIAH HENRYSON DOHERTY.

Josiah Henryson Doherty is one, whose claims on us, as an African Leader, cannot be doubted, an inch; born in August 16, 1866, of poor parents, Henry Doherty the father, of Egbado tribe, and Ariwoọla the mother; young Josiah in after years was admitted as student in the C.M.S. Training Institution in this place, where he was for sometime, until a quarrel took place between him and a schoolmate, he was oblidged to leave; he was recommended by a friend, then a Government Official in the Civil Service of those days; Josiah Doherty was successful in obtaining a situation, for he

was engaged by that gentleman Seidu Olowu to whom he has been previously recommended; this was in 1888. At this time, Seidu Olowu had his business establishment at a place at Massey Lane; now known to us as Vincent Street; later on, he removed his business to his present place of abode—Idunmagbo; and he on observing young Josiah's abilities and intelligence, at once placed him over those he met there, amongst whom were one Ajayi and Muse Kosoko; during this time, Josiah Doherty was staying at his parents' ground-house at Faji Market, now made a storey-house by him. He was in Seidu Olowu's employ for about 6 years, at the end of which, he started business of his own, something in 1891.

At first, he rented a piece of land out from a man named Kabiyawu at Alakoro, this place was formerly one of the real properties of the Reversible Johnson; here he commenced trading on a small scale; after some years he bought lands from the Government at 1d per foot—all being very swampy—to which he removed, and on which he built his business premises, in which he is at the present day. In 1896, Mr. Doherty stopped trading in spirituous liquors of all kinds, mainly through the influence of his mother, who was strongly imbued with the Christian spirit, which naturally convinced her, that a professing Christian ought not to be found engaged in any business that will tend to the physical and moral ruin of his fellow-men. I must not forget to say that when Mr. Doherty started his own business, it was with his own cousin the late Fred Doherty; they two were known and adressed in the merchantile world of those days as "J. & F. Doherty": but subsequently, they were obliged to separate their joint business by mutual consent. In 1896, Josiah Doherty warmed his new building—a storey-house at Campos Square; to his house warming he invited all the school children of St. Peter's day school, besides a host of other guests, and satisfied each and all, in respect of the good things that were provided for them. In commercial life, Josiah Doherty towers high above his contemporaries being a very successful merchant, as his business establishment at Alakoro testifies; in public life, he is popular, winning the hearts of the people, chiefly by his natural kind-heartedness and generousity; in religious life, he is an exemplary and staunch Christian, always implanting such good spirit in the tender minds of all his children; generally, Mr. Doherty is kind and liberal, has contributed largely towards the Pro-Cathedral Fund and other public institutions.

---

ORI III.

## IWA—EGBẸ KIKO ATI APẸRẸ

*(Translated from "Character by Dr. Smiles")*

APA KEJI.

---

A ma nsọ pe nipa ẹgbẹ ti enia ba nko ni a fi mọ iru ẹni ti oluwarẹ jẹ. Ẹniti oju rẹ dilẹ ki isaba ba ọmuti enia k'ẹgbẹ pọ; enia ti o ja fafa ki iba ẹni wuruwuru rin, oniwa rere ki iba onişekuşe rin.

Ti ẹnikan ba nba enia jagbajagba rin, o jẹ pe on papa ni ẹran iwa aidara lara, ti a ba si nri pẹlu wọn nigbakugba, ko si ọgbọn rẹ ti iwa rẹ ko ni fi bajẹ.

Seneca ni "ọrọ ẹnu iru awọn ẹni bẹ a şe ibi nlanla; ki a tilẹ ni ko şe ọşẹ lẹsẹkẹsẹ, sibẹ a wọ inu ọkan lọ, ki ifi ni silẹ, bi o tilẹ jẹ pe ẹniti o sọrọ na ti lọ kuro lọdọ ẹni—arun buburu ti ko ni şai yọju nijọ miran."

Bi a ba fi ọna ti o tọ ati eyiti o yẹ kọ awọn ọdọ ti awọn papa na ba si nfi tọkantọkan sa ipa wọn, nwọn yio wa awọn ẹniti o san ju wọn lọ ba kẹgbẹ, nwọn yio si sa ipa lati tẹle wọn.

Nipa biba awọn enia rere k'ẹgbẹ, ẹda a ma ti iwa rere jẹ sanra dagba; şugbọn biba awọn enia buburu k'ẹgbẹ ki imu ohun kan wa ju ibi lọ. Awọn kan wa ti o jẹ pe ọranyan ni ki a ni ifẹ fun wọn, ki a bu ọla fun wọn, ki a si ma gba fun wọn; awọn miran si wa ti iwa wọn a mu ni karaba fun wọn, ki a si korira wọn,—eyiti Rabelais sọ nigbati o nsọro nipa ti ẹkọ Gargantua, "Mimọ na jẹ ti omugọ." Ba awọn ọmọluwabi gbe pọ, iwọ yio si ri pe nwọn yio fi iwa ati imọ wọn gbe ọ ga soke.

Owe Spanish ni "Ba awọn ikoriko gbe pọ, iwọ na yio si mọ gbo."

Ilopọ pẹlu awọn enia ti ko jamọ nkan, awọn ẹniti o jẹ ti ara wọn ṣa ni nwọn mọ, le ṣe ọṣẹ lọpọlọpọ nip: sisọ ni di alai le ro ero, alai ni igbadun, ki a ma sa ara fun awọn ẹlẹgbẹ ẹni, ati ki a di anikanjọpọn, awọn eyiti ki ijẹ ki a to enia, ti ki ijẹ ki a ni iwa to.

Nigbati o ṣe ero rẹ a kuru, ifẹ danyindanyin kan ko ni si ni ọkan rẹ, ọkan rẹ a sebọ, a si di ẹniti ko ni ọkan ara rẹ, a dẹ ara silẹ fun iwa aimọ, awọn eyiti ki ijẹ ki enia le ṣe iṣẹ rere kan tabi ki o ni iwa rere.

Ni ida keji, biba awọn ẹniti o gbọn ju ni lọ' awọn ti o san ju ni lọ, ati awọn ti o ni oye ju ni lọ k'ẹgbẹ a ma mu ni lọ siwaju, a si ma fun ni ni okun. Nwọn a tubọ ṣe iranlọwọ fun ni lati mọ bi aiye ti ri. Awa a fi ero wọn tun ero tiwa ṣe, awa a si jumọ ma ba wọn lo ọgbọn ti nwọn ni. Awa a tọrọ oju wọn kun tiwa ki a ba le ri oye ju bi a ba ti ri lọ, awa a fi ọgbọn won ṣe ọgbọn, ki isi ṣe ninu igbadun ti nwọn ri nikan ni a ma nkọgbọn, ṣugbọn ninu eyiti o kọ ni ni ọgbọn ju—ninu iya jijẹ wọn pẹlu.

Bi nwọn ba ni agbara ju wa lọ, awa a ma wọn jumọ lo agbara ti nwọn ni. Nitorina ni biba ọlọgbọn ati alakikanju enia k'ẹgbẹ pọ ni agbara iyebiye lori iwa ti enia nhu—a tubọ mu ni ni ero, a fun ipinnu wa ni okun, a gbe ohun ti a ba nlepa yọ, a tubọ mu ni le tọju nkan ti ara ẹni lakoko ati pẹlu ọgbọn, a si tubọ le jẹ ki a ran awọn ẹlomiran lọwọ ju bi a ti le ṣe ri lọ.

Mrs. Schimmalpennick ni "Nigbagbogbo ni o ma ndun mi de ọkan: adanu ti mo pa nipa iwa anikanjẹ ti mo ni lọwọ nigba ewe. Ko si ẹgbẹ bubnru kan ti o ju ki enia ti ko ti ini ọgbọn ya aṣo lọ, ki iṣe pe oluwarẹ a di ẹniti ko mọ ọna ti a gba ran awọn ẹlẹgbẹ ẹni lọwọ nikan ni, ṣugbọn ko tilẹ ni ni oye ibi ti o yẹ ki a ṣe iranlọwọ si.

"Bi ẹgbẹ kiko ko ti gba ni ni akoko ti a fi isimi, a le sọ pe eyi a mu ki enia tubọ ni oye si; ati pe ifẹ ti yio si ti ibẹ yọ, bi o tilẹ jẹ pe ko dabi anu ti iti ọkan wa, ki iṣai mu ere nlanla wa fun ni.

"Ẹwẹ, ẹgbẹ kiko si dara ni ti pe a tubọ mu iwa ẹni duro dede, a si mu ni rin lọna ti o tọ ati eyiti o yẹ lai ṣina."

Ki a gba ọdọmọkọnrin ni ero rere kan, ki a fi oye kan ye ni asiko ti o wọ, tabi ki ọrẹ totọ fun ni imọran, eyi le dari rẹ si ọna miran laiye, o le mu ṣe iṣẹ miran yatọ si eyi ti ọkan rẹ ti mu lati ṣe. Bayi ni o ri ni ti Henry Martyn, Ojiṣẹ Ọlọrun ni India: nigbati o wa ni ọmọ ile-'we ni Truro Grammar School, o dabi ẹnipe ọrẹ ni o dari rẹ si ọna ti o wa mu tọ nigbati o dagba. Martyn papa jẹ olokunrun ọmọ. Nitori eyi ko saba ma ba awọn ẹlẹgbẹ rẹ ṣe awọn ire orişirişi ti ọmọ ile-'we ma nṣe; ati nitoripe a ma ṣe bi ọmọ agbo, awọn ọmọ ti o dagba ju lọ a ma tọ lẹran, awọn miran a si ma halẹ mọ. Ṣugbọn ọkan ninu awọn ọmọ ti o dagba ju lọ fẹran Martyn, o fa mọra, o si duro ti, ki iṣe kiki pe a ma gba ija rẹ kanri nikan ni, ṣugbọn a ma ṣe iranlọwọ lati fi iwe ti o nkọ ye pẹlu. Martyn jẹ ọmọ ti o rẹhin ninu iwe, ṣugbọn baba rẹ nfẹ ki o lọ si ile-'we giga (*College*); nigbati o si di ọmọ ọdun mẹdogun, o ran lọ si Oxford, boya yio le gba Corpus Scholarship, ṣugbọn pabo ni. O tun ṣe ọdun meji si ni Truro Grammar School, lẹhinna o wa lọ si Cambridge—St. John's College. Tani a ro pe o tun ba nibẹ, bikoṣe alafẹhinti rẹ kanna ti Truro Grammar School?

Nwọn tun bẹrẹ si ṣe ọrẹ; lati igbana ni eyi agba ti duro ni iduro ogboni fun eyi kekere.

Martin ko ṣe dede ninu iwe rẹ, bi o mura si loni, bi o di ọla a rẹwẹsi, a binu, a ṣe bi ọmọde, nigbamiran a binu gbanrangandan ti enia ko ni ri oju rẹ ti okun bọ. Ṣugbọn ọrẹ rẹ jẹ ẹniti dun dede, ti o ni suru ti o si mura si ṣẹ ko si dẹkun ma ṣe alabojuto, olutọ-sọna ati olumọran ekeji rẹ onikara, eyiti o ṣe ni ire ko jẹ ki o ko ẹgbẹ bubru, o gba ni imọran ki o mura si iṣẹ—ki ṣe iṣẹ "fun iyin enia, ṣugbọn fun ogo Ọlọrun"—bẹ ni o ran lọwọ ninu ẹkọ rẹ, tobẹ ti o fi wa ni ipo ekini larin awọn ẹgbẹ rẹ ninu idanwo ti nwọn ṣe ni ọdun (Christmas) ti o tẹle. Ṣugbọn ọrẹ ati ọgbọn Martin, papa ko de ipo nla kankan, a ko gburo rẹ mọ, boya o wa nibi ti o nṣe iṣẹ rere, ṣugbọn ti ko ni okiki; ifẹ ọkan rẹ laiye ni pe ki on le tun iwa ọrẹ on ṣe ki o mu ọkan rẹ ni ifẹ fun otitọ, ki o si mu gbaradi fun iṣẹ rere ti o wa bọ si laipẹ lẹhin eyi—iṣẹ ti ojiṣẹ Ọlọrun ni India.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

***OLUSAKIN'S COLUMN.***

---

**How are the Mighty fallen.**

We deeply regret to announce the death of our respected Townsman, the Merchant Prince Josiah Henryson Doherty, Esq., of "Doherty Villa", 5 Campos Square, Lagos, which occurred on Saturday afternoon, the 24th March, 1928, at 4.35 p.m.

The funeral service took place the following day the 25th instant, at Christ Church Pro-Cathedral at 3.15 p.m., before a large multitude of people.

The Right Rev. Bishop I. Oluwole, D.D., Rev. M. S. Cole, M.A., and Rev. J. O. Lucas, M.A., officiated. The Church was crowded to overflowing and every available space in the Church yard was packed to the utmost. Odunlami Street, Broad Street and the Marina were blocked by motor cars numbered over 300 intended for the funeral, and the interment took place at Ikoyi Cemetery.

The fact of his illness became known about a month ago, but the seriousness of his condition was not realized until it was rumoured that he was suffering from Ulcer in the stomarch. He was attended to by many Doctors including his son.

The late Mr. Doherty was an exemplary Christian, a regular Church goer, sympathetic, kind, social generous and liberal to a fault.

Mr. Doherty's name shall always be remembered in Nigeria and its environments: he died but yet speaketh.

Mr. J. Henryson Doherty met his death without any remorse, and expressing, as we are told, to some of his children and friends that he was ready to die and not afraid of death.

He was of many wives and no less than 38 children.

To his wives, children, and to his friends Rt. Rev. Bishop A. W. Howells, Messrs. J. H. Stanley Robbin, F. Germano Martins, E. A. Motajo, F. A. Thomas, Yesufu Adebayo Ijale and the relatives of the deceased, our profound sympathy. May he rest in peace.

### Prohibition of Submarines.

Mr. Kelly, United States Secretary of States, informed the Foreign Affairs Committee of the House of Representatives on Saturday that the Government would "be willing to sign a treaty with all the Powers of the world prohibiting the use of submarines entirely."

### Archbishop of Canterbury 25 years' Primacy.

It was on Thursday, February 12, 1903, that Dr. Davidson was enthroned in the presence of a large congregation. An important part in the ceremony was taken by the late Dean Farrah and Lord Rosebery was among those present.

---

Dr. Randall Davidson, who on Sunday the 12th February last commemorate the 25th anniversary of his enthronement as Archbishop of Canterbury will be 80 in April next, and will celebrate his golden Wedding in November. Mrs. Davidson is a daughter of the late Archbishop Tait.—*The Times Weekly Edition, 9th & 16th February, 1928.*

### Rev. James Pearse.

Rev. James Jameison Pearse, L.Th., Pastor of St. Jude's Church, Ebate Meta, met with an accident on Friday night the 23rd instant at the Parsonage when a nail on a window frame stuck him on his right eye. Rev. C. A. Ṣowunmi, M.A., Curate of St. Paul's Church, Breadfruit, Lagos, occupied his pulpit last Sunday the 25th instant.

We wish Rev. Pearse early recovery to resume his Pastoral duties.

### King's College, Lagos.

A successful Concert for the term end took place at King's College, on Tuesday, the 27th March, 1928, at 8 p.m.

OLUṢAKIN.

---

## IFẸ' NEWS.

On Tuesday the 13th March, 1928, the members of "Egbe Agba-o-Tan" of Ibadan, *i.e.*, the Rev. J. Okuseinde, Rev. D. O. Williams, Hon. E. H. Oke, Salami Agbaje, Esq., D. Obasa, Esq., Obisesan, Esq., and others paid a visit to their President the Oni of Ife to sympathize with him on the occasion of the death of his brother Prince Ojo Adeyeye [Aremoh].

## THINGS WE WANT TO KNOW.

1. Are women in excess? It is observed very rightly too, that in every gathering whether religious, social or political assemblage, the attendance of womenfolk is in the average more than the men. Can the Census Officer explain why?

2. East is East, and West is West, what is really the difference between the White and Blackmen; is it the colour, or the stuff of brains? Can the shades of Shem, Ham, and Japheth explain?

3. An inquisitive father who has twin sons is very anxious to know who is the natural and legal heir between Kehinde and Taiwo; surely not both?

4. England expects every one to do his duty:— A story is told of an official formerly we are told the Boss of a certain Degartment who goes round as frequently as he likes on his usual rounds he generally enquires from his subordinates the following questions "Any signalling cough" "Any whispering gossips" Any back answer, to which his subordinates replied—no Sir—everything all right—he reported, more work, less talk. Is this not commendable?

5. The playing of the Police Band was good, the music was sweet and soft to one's hearing, on enquiry shews no difference even when Field holds his baton?

6. Is it advisable for Married Couples to stay together with their-in-laws, especially with an uncompromising ill tempered mother-in-law. Will ladies please say?

7. Are we not in need of Female Doctors in the Hospitals, as well as in the town especially as there is great demands for such services as to confinements of the fair sex. We welcome such advent.

8. Seeing is believing; you cannot buy a pig in the bag as the maxim goes; you would prefer to see the articles before purchasing?

9. A man is said to be the Architect of his own fortune, who then is the bricklayer?

10. It is not uncommon to see some blind beggars go about in the night begging alms from door to door. Are they really blind? Can the Police please say.

11. Why scanty seats are provided without shelter for the public who do business in the new Police Court?

MARY BULL.

# JUST ARRIVED.

## ANTI-GON PILLS

***4/6d per bottle of 72 Pills.***

A reliable antisceptic for Urinary Disturbances.

## LIFE TONIC TABLET

(AJIDEWE).

***4/6d, An efficacious "pick-me-up."***

## FEMALE WIRELESS PILLS NO. 1

***4/6d. For all monthly Disorders peculiar to Females.***

## KADUNA BALM

(IPARA AWO'GBA ARUN).

***1/-. Can be applied in 100 different ways !!!***

## "WALK EASY ANTI-RHEUMATIC SALT"

(OGUN LAKUREGBE).

***3/6d & 2/-.***

Sold only by:—

***K. B. SAVAGE,***

IYIN OLUWA MEDICINE STORE,

*Head Office*:—88, Broad Street,

*Branches at*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109, Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by Victor White, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—Not Obtainable Elsewhere.
"Shake the Bottle."

### REMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price Ten Shillings (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as :—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by Victor White Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

Price 10/- Per Bottle.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, Offin Road, Lagos.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe, awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy for Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
Victor White, Esq, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".
Price Ten Shillings (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko bela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality !! Quick Fortune !!!

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

# TO LET.

## One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko,

—— :o: ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọm ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọ si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aşetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi a awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fu ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.